## N. C. N. C. ko ni ibo

OGBODO ya ẹni ti o ba ni lakaye lẹnu lati ri i pe Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) "ngbidanwo" lati fi han pe awọn wa nibẹ ninu idibo ti nwọn yio ṣe lati wọ Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni ọjọ kẹrindilogbọn oṣu yi.

Idi iyanu na ni pe lati igbati Ẹgbẹ Alakukọ ti jẹ gaba si ilẹ Ibo kini anfani ti nwọn ṣe nibẹ? Pataki ni ẹkọ-iwe jẹ fun gbogbo awọn ọmọde l'okunrin ati l'obirin nitoripe ogun ti ki i tan ni o jẹ fun wọn.

Dipo ki Ijọba Ẹgbẹ Alakukọ fi ṣe iranwọ fun awọn ọmọde ninu ẹkọ-iwe, nṣe ni nwọn ko bikita lati fun wọn l'ẹkọ na. Nwọn kọ lati san owo awọn oluko wọn. Nitorina ni ọpọlọpọ ile-iwe Ibo fi wa ni titi. Ko si ọmọluwabi ninu Yoruba ti yio fẹ lati dibo fun wọn wọ'le Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun. E maṣe dibo fun wọn, ẹ ma jẹki nwọn fun tan nyin danu.

Emi ni,
Y. AYINLA DISU.
Eko.

## Ẹ ku abọ ẹnyin arinrin-ajo

ENU ko gba ọpẹ ni irin-ajo ti Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria, Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ati awọn ẹmẹwa rẹ rin fun idagbasoke Naijiria, paapa Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria, jẹ. Mo ki ẹnyin arin-rin-ajo na pupọ, ẹ ku'ṣe.

O dun mọ mi pupọ, mo si ba nyin yọ nitori Eni-Mimọ-Julọ ilu Romu, Popu Pius Kejila Olori gbogbo Ijọ Aguda yika azabaiye gba nyin l'owo l'ẹsẹ (gba nyin pẹlu ibukun Oluwa). Ibukun na yio ma a bẹ pẹlu nyin titi lai-lai.

Ẹ ku abọ! ẹ ku ori ire!!

Emi ni,
D. O. FABODE.
Ibadan.

## Ejinrin nfẹ ẹrọ Asọ'rọ-ma-gb'esi

ILU Ejinrin jẹ ọkan ninu awọn ilu ti ki i fi ofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ṣere (ki i tapa si ofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun rara). Ṣugbọn abuku pataki ni o jẹ fun ilu yi fun alaikoni ẹrọ asọrọ-ma-gb'esi (radio).

A bẹ Ijọba ki nwọn ba wa fi ẹrọ asọrọ-ma-gb'esi na si ilu yi. Bi nwọn ba ṣe bẹẹ, inu awa ara ilu yio dun pupọ, a o si dupẹ.

Emi ni,
*Oloye Rashidi Raji Balogun*
Ejinrin.

## O dun mọ mi

INU mi dun nigbati mo ka Iwe Irohin Yoruba ni Ile-Ifẹ pe yio bẹrẹ si ma jade lẹmeji l'ọsẹ-ọsẹ.

Adura mi ni pe Olawa Olodumare yio ma ran nyin lọwọ. Laipẹ, ẹ o tun le maa jẹki Iwe Irohin Yoruba yi maa jade lojojumọ.

Mo ki Olotu ati awọn Oludasilẹ Iwe Irohin Yoruba ati awọn oṣiṣẹ nyin, ẹ ku iṣẹ o. Mo si bẹ nyin pe ki ẹ tubọ ma a ba wa tuna aṣiri awọn Jagunlabi nitoripe Ibo ni nbo. Ẹgbẹ Olọpẹ ni yio bori lagbara Edumare.

Emi ni,
J. O. SHOYINKA.
Ile-Ifẹ.

## Nwọn gbe Anifalọba gun aayan

NKAN nla ni redio ati iwe irohin nṣe. Awọn mejeji nran wa lọwọ lati bo lọwọ itanjẹ. Gbogbo ohun ti nlọ laiye ni a ngbọ loni. A mọ wipe loni Afẹnifẹre ni a le pe ni ẹgbẹ ti o to ẹgbẹ gan an ni Iwọ Orun Naijiria. Nwọn ni enia, nwọn ni iwa nwọn si ni owo.

Mo mọ awọn alakukọ. Mo ti gbe arin wọn ri. Nwọn ko ni enia. Nwọn ko ni iwa. Awọn alakukọ yan arakunrin mi kan ti a npe ni Anifalọba fun Igbimọ Aṣofin nla ti nwọn fẹ dibo fun laipẹ yi. Ohun abuku tilẹ ni wipe ẹgbẹ ti o to ẹgbẹ ki o ma ri enia fakalẹ afi Anifalọba. Kini Anifalọba yi mọ nipa iṣelu. Bi nwọn ba nso Ijinlẹ Oyinbo Anifalọba paapaa yio maa wa ongbufọ ni.

Awa ni a yan Anifalọba ni Kansilọ. Ko ṣe iṣẹ Kansilọ na daradara. Awa ara adugbo rẹ si pejọ a sọ wipe a ko fẹ ẹ ni Kansulu mọ. A sọ wipe a ko ni igbẹkẹle si i fun iṣẹ rẹ ni Kansulu. On paapaa mọ eyiyi. Gbogbo adugbo wa ni nwọn mọ wipe Anifalọba ko ṣe iṣẹ Kansulu de ibiti o gbe tẹ wa lọrun. Baiti o ṣe iṣẹ Kansulu kekere bi tiwa ti na ni awọn alakukọ wa le lọ yan ki o wa lọ si Igbimọ Aṣofin nla ni Ibadan? Awọn alakukọ paapaa ko le ṣaimọ pe Anifalọba ko tẹwọn to fun iṣẹ yi. Emi ro pe nwọn fẹ gbe gun aayan ni. Igba gbon'mi o ti i. ẹru apẹrẹ ni?

Kini Anifalọba tilẹ ṣe fun Ogbomọṣọ ri? Ninu eto ilọsiwaju ilu wo ni a ti gbọ oruko rẹ ri? Tani mọ Okolo rẹ l'Ọyọ? Lakaye melo ni ọmọkunrin na ni lati fi ṣe iru iṣẹ bantabanta ti ipo yi npe fun? Ṣugbọn bi eke ba ro ẹlọ ika kọ ni yio du a. Ogbomọṣọ kii ṣe were. Awa ko nii dibo fun Anifalọba. A ko nii dibo fun akukọ tabi iyekan akukọ to nje kokurọ. OPẸ ni awa o dibo fun. Tobatọba wa, tijoyetijoye wa, tayatayа, ati tomotomo wa. OPE NI A O DIBO FUN. Bi Anifalọba paapaa ko ba dibo fun OPE ekurọ Ifa le bere lowo re. E DIBO F'OPE.

Emi ni,
JIMỌ KASALI
Ita Alasa, Ogbomọṣọ.

Ẹ dibo F'Ọpẹ








## Ẹ dibo fun Ẹgbẹ Afẹnifẹre






# Ẹ dibo f'Ọpẹ




THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED



O ngmu ọmọ - ọwọ
lagbara ati ilera
nigbati o ba
fẹ hu ehin



Ashton & Parsons
*Infants' Powders*


# Awọn Aṣoju ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre yan sode lati dibo fun



NDUKA EZE
Asaba North



ALHADJI ADELEKE
Oyo Central



S. O. FADUN
Badagry East



T. A. ODUTOLA
Ijebu Central



A. ADEDOYIN
Remo South



S. O. IGHODARO
Benin East

# Ẹ DIBO FUN ỌPẸ



TONY ENAHORO
Ishan East



D. ADELEKE ADEMILUYI
Ife Central

## WESTERN REGION PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

*Lati oju ewe keta*

roba afi lati le gbe e de ile-iṣẹ.

Opolopo awọn irin-iṣẹ ile-iṣẹ na ni a ni lati ti ra sile ni Naijiria tipẹ-tipẹ lati ilo okere lati ri i daju pe nwọn ti pe'ju silẹ ki a to kọ ile-iṣẹ na. Nipa ayọrisi eto atata ti a ni lati tun ko ile-iṣẹ kan eyi ti yio jọ ti Ikpoba pupo, ti a ti sọ fun nyin nipa rẹ, a o ti kọ ọ pari ki wọn igi roba na to bẹrẹ si ni oje.

OWO TI O PE

17. Bi oko na ba gberu tan a ni ireti pe iṣẹ roba yi yio ma a mu owo ti yio fẹrẹ to ogun ọkẹ ponun (£400,000) wọ'le l'ododun. Eyi le fi han ni pe dida oko yi silẹ jẹ owo ti o pe wa, ni Ipinlẹ Iwọ-Orun, eyi ti a fi owo wa ṣe. O si jẹ apẹrẹ daradara ti awọn agbẹ Ipinlẹ yi le maa tẹle fi sisẹ.

18. A ti tun nda oko roba kan silẹ ni Araromi, eyiti a ro pe o to ẹgbaata ilẹ (6,000 acres) a o si pari re titi ọdun mẹta.

19. Agbegbe Ibinni ati Delta ti Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria dara lati ma a gbin roba si, a si ti fi han pe rọba wa jẹ ọkan ninu awọn rọba ti o darajulọ l'aiye yi. A fẹrẹ pari ti Urhonigbe a si ti bere ti Araromi. Igbimọ yi yio ma a fi si ero nigbagbogbo lati tun da awọn oko roba miran silẹ. Nipa bayi, a nṣe eto lati ri i pe a ko fi igbẹkẹle wa s'ori koko nikan mọ. Nitoripe on ni a mọ pe oni'ye lori ju, ti o si jẹ pataki fun wa ju, bena ni yio si ma a jẹ ohun ogbin pataki fun wa nigbagbogbo. Ni Ipinlẹ Iwọ-Orun, oko koko ni yio jẹ oko ogbin ti a ni pọjulọ ninu gbogbo oko ogbin wa ti a ti da silẹ. A o si ma a sọ fun nyin nipa re ni kikun nigbamiran.






Printed by the Amalgamated Press of Nigeria Ltd., 5/7 Apongbon Street, Lagos. Editor: S. M. Ademuyiwa, Chapel Street, Lagos.